Ko si ẹni kankan ti o n jẹrii pe ko si ẹni ti ijọsin tọ si lododo afi Allahu, ati pe Muhammad ojiṣẹ Ọlọhun ni lododo lati inu ọkan rẹ, afi ki Ọlọhun ṣe ina leewọ fun un

Láti ọdọ Anas ọmọ Maalik- ki Ọlọhun yọnu si i- pe: Mu'aadh wa lẹyìn Anabi- ki ikẹ Ọlọhun ati ọla Rẹ maa ba a- lori nnkan ọgun, o sọ pe: "Irẹ Mu'aadh ọmọ Jabal", o sọ pe: Mo n da ẹ lohun irẹ ojiṣẹ Ọlọhun, mo si n wa oriire fun dida ẹ lóhùn, o tun sọ pe: "Irẹ Mu'aadh", o sọ pe: Mo n da ẹ lohun irẹ ojiṣẹ Ọlọhun, mo si n wa oriire fun dida ẹ lóhùn, lẹẹmẹta, o sọ pe: "Ko si ẹni kankan ti o n jẹrii pe ko si ẹni ti ijọsin tọ si lododo afi Allahu, ati pe Muhammad ojiṣẹ Ọlọhun ni lododo lati inu ọkan rẹ, afi ki Ọlọhun ṣe ina leewọ fun un", o sọ pe: Irẹ ojiṣẹ Ọlọhun, njẹ mi ko nii maa sọ ọ fun awọn eniyan ki wọn le dunnu? O sọ pe: "Ti o ba ri bẹẹ wọn maa gbara le e". Ni Mu'aadh wá sọ ọ́ nigba ti o fẹ ku ki o ma baa kó sínú ẹṣẹ.

[O ni alaafia] [Ohun ti wọ́n fi ẹnu kò lé lórí ni]

Mu'aadh ọmọ Jabal- ki Ọlọhun yọnu si i- wa lẹyin Anabi- ki ikẹ Ọlọhun ati ọla Rẹ maa ba a- lori nǹkan ọ̀gùn rẹ, o wa pe e: Irẹ Mu'aadh? O paara pipe e rẹ lẹẹmẹta; lati fi pataki nnkan ti o fẹ sọ rinlẹ. Ati pe gbogbo ìyẹn ni Mu'aadh- ki Ọlọhun yọnu si i- n da a lohun pẹlu ọrọ rẹ pé: "LABBAEKA YAA ROSUULALLOOHI WA SAHDAEK", o n túmọ̀ sí pe: Mo n da ẹ lohun irẹ ojiṣẹ Ọlọhun ni idahun kan lẹyin idahun, mo si n tọrọ oriire fun jijẹ ìpè rẹ. Anabi- ki ikẹ Ọlọhun ati ọla Rẹ maa ba a- sọ fun un pe ko si ẹnikẹni ti o n jẹrii pe LAA ILAAHA ILLALLOOH, itumọ rẹ ni pe: Ko si ẹni ti a le jọsin fun pẹ̀lú ẹ̀tọ́ afi Ọlọhun, ati pe dajudaju Muhammad ojiṣẹ Ọlọhun ni, lododo lati inu ọkan rẹ lai parọ, ti o ba ku lori iṣesi yii, Ọlọhun maa ṣe ina leewọ fun un. Mu'aadh- ki Ọlọhun yọnu si i- wa beere lọwọ Anabi- ki ikẹ Ọlọhun ati ọla Rẹ maa ba a- pe ṣe ki oun sọ ọ fun awọn eniyan ki wọn le yọ ki wọn si dunnú si dáadáa? Anabi- ki ikẹ Ọlọhun ati ọla Rẹ maa ba a- wa paya pe ki wọn ma baa gbara le e, ti iṣẹ wọn fi maa kere. Mu'aadh ko sọ hadiisi naa fun ẹnikẹni afi ṣiwaju iku rẹ; ni ti ipaya kikosi inu ẹṣẹ fifi imọ pamọ.

http://www.sunnah.global/hadeeth/yo/show/10098